Hello and welcome to Binogi. My name is Rosalia, and I'm one of the research assistants with The ESCAPE Projects. Today, I am going to show you how Binogi can be used at home with your child.

Káàbọ̀ sí Bìnógì. Orúkọ mi ni Ròsálíà, Mo sì jẹ́ ọ̀kan lára àwọn olùrànlọ́wọ́ ìwádìí nínú iṣẹ́ àkànṣe ESCAPE. Lónìí, n ó máa ṣe àfihàn bí ó ti lè lo Bìnógì ní ilé pẹ̀lú ọmọ rẹ.

Binogi is an online learning tool that provides educational videos for math and science. Your child's teacher will use Binogi in various ways: they can use the videos before, during, and/or after the lesson in class. They can also create assignments for students to watch the video and do the quizzes at home.

Bìnógì jẹ́ ohun èlò ìkẹ́kọ̀ọ́ orí ayélujára tí ó pèsè àwọn fídíò ìkẹ́kọ̀ọ́ fún ìmọ̀ ìṣirò àti sáyẹ́nsì. Olùkọ́ ọmọ rẹ yóò lọ Bìnógì ní oríṣiríṣi ọ̀nà: wọ́n lè lo àwọn fídíò náà ṣáájú, nígbà tí, àti/tàbí lẹ́yìn ìkẹ́kọ̀ọ́ ní yàrá ìkàwé. Wọ́n tún lè ṣẹ̀dá àwọn iṣẹ́ àyànṣe fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti wo fídíò náà kí wọ́n sì ṣe àwọn ìbéèrè ní ilé.

Once your child has a Binogi account, this is how their Binogi homepage looks like. As you can see, their recent activities are displayed, so you can easily check what your child is learning at school. If videos and quizzes are assigned to your child by their teacher, this is how it looks like on their homepage. The name of the Binogi lesson, tasks, and due date and time are indicated.

Ní kété tí ọmọ rẹ bá ní àkóùntì Bìnógì, báyìí ni ojú ilé Bìnógì wọn yóò ṣe rí. Gẹ́gẹ́ bí o ti ri, àwọn iṣẹ́ tí wọ́n ṣe láìpẹ́ hàn, kí o lè ṣàyẹ̀wò ohun tí ọmọ rẹ ń kọ́ ní ilé-ìwé ní ìrọ̀rùn.

Bí olùkọ́ ọmọ rẹ bá yan àyànṣe fídíò àti ìbéèrè fún un, báyìí ni yóò ti rí ní ojú ilé wọn. Orúkọ ẹ̀kọ́ Bìnógì náà, àwọn iṣẹ́ ṣíṣe, àti ọjọ́ àti àkókò tí ó yẹ láti gbà á yóò di mímọ̀.

For this video, let’s say that your child has already watched a video on “The History of Climate Change” and did Quiz 1 at school, and you would like to review the lesson with your child. You can either click it under “Your Activities” or type it in the search engine.

The video has a number of features: 1) There is a transcript below the video; 2) you can control the speed; 3) you can rewind the video a few seconds; and 4) you can choose a language for the spoken language and subtitles. For example, let’s say your first language is Dari. You can select “Dari” as the spoken language and choose “English” for subtitles.

Fún fídíò yìí, ká ní pé ọmọ rẹ ti wo fídíò lórí 'Ìmọ̀ ìtàn nípa ìyípadà afẹ́fẹ́' tí ó sì ṣe ìdánwò 1 ní ilé-ìwé, tí o sì fẹ́ láti ṣe àtúnyẹ̀wò ẹ̀kọ́ náà pẹ̀lú ọmọ rẹ. O lè tẹ̀ ẹ́ lábẹ́ 'Àwọn iṣẹ́ àmuṣe rẹ' tàbí kí o tẹ̀ ẹ́ nínú ẹ̀rọ ìṣàwárí.

Fídíò náà ní àwọn àbùdá bíi mélòó kan: 1) Tíráńsíkírípìtì kan ń bẹ ní ìsàlẹ̀ fídíò náà; 2) o lè ṣàkóso ìyára fídíò náà; 3) o lè ṣe ìdápadà sẹ́hìn fídíò náà fún ìṣẹ́jú díẹ̀; àti pé 4) o lè yan èdè kan fún èdè tí a sọ àti àwọn àtúnkọ. Fún àpẹẹrẹ, ká ní pé èdè àkọ́kọ́ rẹ ni Dárí. O lè yan "Dárí" gẹ́gẹ́ bí èdè tí a sọ, kí o sì yan "èdè gẹ̀ẹ́sì" fún àtúnkọ.

When you watch the video with your child, you can use this ‘play’ and ‘pause’ button to stop the video and converse with your child about

the content at any time. You can also ask your child to tell you about the lesson before watching the video together. We encourage you to share your experiences regarding the topic as it will enrich the discourse with your child. For example, you might have experienced a natural disaster due to the climate change in your home country or while you were travelling. Sharing your stories will not only increase your child's motivation and engagement in learning, but also provide an opportunity for them to inquire further and do their own research. Also, depends on the topic and your stories, it can help your child to broaden their perspectives and learn more about your or other cultures and countries.

Bí o bá wo fídíò náà pẹ̀lú ọmọ rẹ, o lè lo bọ́tìnì 'wò ó' àti 'dádúró' láti dá fídíò náà dúró kí o sì bá ọmọ rẹ sọ̀rọ̀ nípa àkóónú fídíò náà ní ìgbàkugbà. A gbà ọ́ níyànjú láti sọ àwọn ìrírí rẹ nípa kókó ọ̀rọ̀ náà nítorí yóò ṣe àlékún ìmọ̀ lórí ọ̀rọ̀ náà pẹ̀lú ọmọ rẹ. Fún àpẹẹrẹ, o lè ti ní ìrírí nípa àjálù àdáyébá látàri ìyípadà ojú ọjọ́ ní orílẹ̀-èdè rẹ tàbí nígbà tí ò ń rin ìrìn àjò. Sísọ nípa ìrírí rẹ kì yóò ṣe àlékún ìwúrí àti ìfarasí ọmọ rẹ nínú ẹ̀kọ́ kíkọ́ nìkan, ṣùgbọ́n yóò tún pèsè ààyè fún wọn láti béèrè síwájú kí wọ́n sì ṣe ìwádìí tiwọn. Bákan náà, ó lè ran ọmọ rẹ lọ́wọ́ láti gbòòrò àwọn ìwòye wọn àti láti ní ìmọ̀ sí nípa àsà rẹ tàbí àwọn àṣà àti orílẹ̀-èdè mìíràn gẹ́gẹ́ bí ó ti ní ṣe pẹ̀lú kókó ọ̀rọ̀ àti ìrírí rẹ.

Lastly, there are 3 quizzes. Like the video, you can change the language. Please note that the quizzes are ordered by difficulty and they consist of multiple choices, fill in the blanks, and written responses. You can either solve the problems together with your child or support them when they need your help.

Lákòótán, àwọn ìbéèrè méta wa. Gẹ́gẹ́ bíi fídíò náà, o lè yí èdè padà. Jọ̀wọ́, ṣàkíyèsí  pe àwọn ìbéèrè náà wà ní ààtò bí wọ́n ṣe le sí àti pé wọ́n ní àwọn ìbéèrè èwo-ni-ìdáhùn, dídí àwọn ààyè tó dófo àti àwọn ìdáhùn kíkọ. O lè yanjú àwọn ìṣòro pẹ̀lú àwọn ọmọ rẹ tàbí ṣe àtìlẹyìn fún wọn nígbà tí wọ́n bá nílò ìrànlọ́wọ́ rẹ.

If you and your child would like to learn more about the topic or related topic, you can easily find videos on those topics by using the search engine. For example, let’s say you and your child would like to learn about “greenhouse gases” after watching “The History of Climate Change”. Type “greenhouse gases” in the search engine, then it will show a list of videos that are related to “greenhouse gases”. It shows that there are 55 videos on “greenhouse gases”. From here, you can narrow down the search by subject and language. You can also find a video with quizzes only by clicking this bar.

Bí ìwọ àti ọmọ rẹ bá fẹ́ láti kọ́ ẹ̀kọ́ si nípa kókó ọ̀rọ̀ náà tàbí kókó ọ̀rọ̀ tí ó jọ mọ. O lè wá àwọn fídíò lórí àwọn kókó ọ̀rọ̀ yẹn ní ìrọ̀rùn nípa lílo ẹ̀rọ ìṣàwárí. Fún àpẹẹrẹ, ká ní ìwọ àti ọmọ rẹ fẹ́ láti kọ́ ẹ̀kọ́ nípa 'èéfín atẹ́gùn' lẹ́yìn wíwo 'ìmọ̀ ìtàn nípa ìyípadà afẹ́fẹ́'. Tẹ, èéfín atẹ́gùn sínú ẹ̀rọ ìṣàwárí, lẹ́hìn náà yóò ṣe àfihàn àwọn fídíò tí ó jọ mọ́ 'èéfín atẹ́gùn'. Ó fi hàn pé fídíò márùn-ún dín lọ́gọ́ta (55)  ló wà lórí 'èéfín atẹ́gùn'. Láti ibí, o lè dín àwọn àwárí kù nípa kókó ọ̀rọ̀ àti èdè. O sì lè wá fídíò pẹ̀lú àwọn ìbéèrè nìkan nípa títẹ igi yìí.

I hope that this video was informative and that you feel more comfortable supporting your child at home with Binogi. Thank you!

Mo ní ìrètí pé fídíò yìí kún fún àlàyé àti pé ó rọ̀ ọ́ lọ́rùn si láti ṣe àtìlẹyìn ọmọ rẹ ní ilé pẹ̀lú Bìnógì. O ṣeun!